# ISẸ ETO ILERA IJỌBA APAPỌ

**Iwe pelebe yi se alaye eto ilera ijọba apapọ (NHS) ni orilẹ-ede UK.**

Eto ilera ijọba apapọ wa fun itọju ara ẹni ni orilẹ-ede UK, owo-ori ti awọn eniyan nsan si ni a nlo fun eto naa. Awọn eniyan ti nwa aabo ni orile-ede miiran nitori rogbodiyan eto oselu ni orilẹ-ede wọn (asylum seekers), ni ẹtọ lati jẹ anfaani eto ilera NHS laisan owo, nigbati a ba si nwadi ohun ti o mu wọn sa kuro ni ilu wọn. Iwo yoo nilo fọọmu HC2, eyiti ile-isẹ ti nsatilẹyin fun ẹtọ awọn ti nwa idaabobo ni orilẹ-ede yi (NASS), tabi awọn ile-itaja oogun nse ipese rẹ, lati le gba oogun lọfẹ, lati le jẹ anfaani itọju eyin ati ẹnu lọfẹ, lati le jẹ anfaani ayẹwo oju ati gbigba jigi iriran lọfẹ.

Ko si eyikeyi ninu awọn osisẹ ile-isẹ NHS <u>ti yoo sọ ohun ti o ba sọ fun wọn fun ẹlomiran, tabi fun ajọ miiran, laijẹwipe o fun wọn lasẹ lati se bẹẹ,</u> eyi si kan awọn dọkita, nọọsi, ati awọn olutumọ-ede papa. <u>Gbogbo itọju ti a o se fun ọ yoo jẹ labẹ asiri, eyi ki yoo si ni ohun kankan se pẹlu idajọ nipa ohun ti o sọ wipe o le ọ kuro ni ilu rẹ.</u>

## Bawo ni mo se le ri iranlọwọ gba fun ailera mi?

Bi o ba nsaisan, tabi bi ọkan rẹ ko ba balẹ nipa ilera rẹ tabi ti ẹnikẹni ninu ẹbi rẹ, lọ ri dọkita ti o wa ni agbegbe rẹ, eyiti a npe ni General Practitioner (GP). Ile-isẹ GP ni a npe ni Surgery tabi Health Centre.

O gbọdọ fi orukọ silẹ pẹlu GP kan lakoko, ki o ba a le ri itọju gba nigbakuba ti o ba nilo rẹ. Lati fi orukọ silẹ, iwọ yoo ni lati sọ orukọ rẹ, ọjọ ti a bi ọ, adirẹẹsi rẹ, ati nọmba foonu rẹ, bi o ba ni foonu. Alatilẹyin rẹ, eyiti o ran ọ lọwọ lati ri ile gbe, yoo mọ awọn ohun ti o ni lati se lati le fi orukọ silẹ ni agbegbe rẹ.

Awọn GP miiran ma nfẹ ki gbogbo eniyan ti o wa si ile-iwosan wọn fun igba akọkọ se ayẹwo ipo ilera wọn. Nọọsi ni ma a saba se eyi. O se pataki fun ọ lati lọ fun ayẹwo yi, biotilẹjẹ wipe o ko saisan.

Bi ile-isẹ iwosan kan ba kọ jalẹ lati jẹki o fi orukọ silẹ, o le beere lọwọ ile-isẹ eto ilera ti a npe ni Primary Care Trust, lati ba ọ wa ile-iwosan ti o le lọ.

## Bawo ni emi yoo se seto ati ri dọkita?

Ki o to le ri dọkita tabi eyikeyi ninu awọn nọọsi ni ile-iwosan, o gbọdọ kọkọ seto ati ri wọn, yala nipasẹ lilọ sibẹ funraararẹ ni, tabi nipasẹ pipe lati ori foonu. O le se ibeere fun nọọsi tabi dọkita ọkunrin tabi obirin, biotilẹjẹ wipe eyi kii see se ni gbogbo igba.

O see se ki o ni lati duro fun ọjọ diẹ, bi riri dọkita rẹ ko ba jẹ kikanju. Bi o ba ro wipe o yẹ ki o ri dọkita ni kiakia, sọ fun ẹniti ngba alejo wọle ni ile-iwosan naa, nigbati o ba lọ seto ati ri dọkita, wọn yoo si jẹki o ri dọkita ni ọjọ naa, bi o ba yẹ bẹẹ. Bi dọkita ba ni oye wipe aisan ti nse ọ le de ibi wipe o ko le wa si ile-iwosan, o le wa ri ọ ni ile.

Riri dọkita ma ngba to iṣẹju maarun si mẹwa. O gbọdọ se eto lọtọọtọ fun ẹnikọọkan ninu ẹbi rẹ ti o fẹ ri dọkita.

Jọwọ rii daju wipe o de ile-iwosan lasiko ni ọjọ ti o ti seto lati ri dọkita, bi o ko ba si le lọ mọ ni ọjọ ti o ti seto rẹ yi, jọwọ rii daju wipe o fi to wọn leti ni ile-iwosan naa.

**Bi nko ba gbọ ede gẹẹsi nkọ?**

Bi o ba nilo olutumo-ede, o gbọdọ sọ fun ẹniti ngba alejo wọle ni ile-iwosan naa, nigbati o ba lo seto ati ri dọkita. Sọ fun awọn osisẹ ibẹ iru ede ti o gbọ, wọn yoo si seto olutumọ-ede fun ọ, tabi ki o se eto olutumọ-ede lati ori foonu. O se pataki wipe ki ọrọ iwọ ati dọkita ye ara yin yekeyeke, ki dọkita naa ba a le mọ ohun ti nse ọ.

**Tani o tun nba GP mi sisẹ?**

- Awọn nọọsi kọ ẹkọ akọyege, wọn si ni imọ ti o ga, ni ilu UK. Awọn a maa bojuto ailera, wọn a si maa fun ni l'abẹrẹ ajẹsara, wọn a maa gba ni niyanju nipa fifi eto-s'ọmọ-bibi, wọn a maa tọju awọn alarun ti o le koko, gẹgẹbii aarun atọgbẹ (diabetes), wọn si le gba ni niyanju nipa ailera ẹni.
- Awọn nọọsi agbẹbi ọmọ (midwife) a maa se itọju awọn alaboyun ati ọmọ ti wọn ba bi. Itọju alaboyun ki o to bimọ ni a npe ni 'ante-natal', itọju rẹ bi o ba si bimọ tan ni 'post-natal'.
- Awọn osisẹ ilera ti nba ni lalejo (Health Visitors) ni awọn nọọsi ti o kọ ẹkọ akọyege nipa itọju awọn ọmọde ati awọn ẹbi wọn, wọn a si maa ran ni lọwọ lati wa ni ipo ilera ni gbogbo igba. Awọn wọnyi le wa ki ọ ni ile rẹ.

**Bi mo ba fẹ ri dọkita ti o ni imọ pataki nipa aisan ti nse mi nkọ?**

GP rẹ ni yoo ma saba se itọju rẹ, ti yoo si mọ boya o nilo lati ri dọkita ti o kọ ẹkọ pataki nipa aisasn rẹ (ti a npe ni Consultant), tabi boya o nilo lati duro fun igba diẹ ni ile-iwosan. Gbogbo eniyan ni ilu UK ni maa duro de igba ti a ba da fun wọn bi wọn ba fẹ ri iru awọn dọkita yi.

Ile-iwosan ni yoo kọ iwe si ọ nipa gbogbo eto ti wọn ti se fun ọ lati ri dọkita onimọ pataki yi. O gbọdọ sọ fun wọn ni ile-iwosan naa bi o ba fẹ ki olutumọ-ede pade rẹ ni ibiti o ti fẹ ri dọkita onimọ pataki naa.

Eto ati ri dọkita onimọ pataki yi le waye, nigbamii, ni ile-iwosan ti o jinna diẹ si ibugbe rẹ, sugbọn o le ri iranlọwọ fun sisan owo mọto gba, bi o ba ni fọọmu HC2.

**Iwe ti a nkọ aarun ti nse ni si.**

Bi a ba ti fun ọ ni iwe ti a kọ aisan ti nse ọ si (eyi jẹ alawọ bulu), jọwọ rii daju wipe o nmu eyi dani nigbakuugba ti o ba ti fẹ ri dọkita tabi nọọsi. Ohun ti a kọ sinu iwe yi jẹ ohun asiri ti o han si iwọ ati awọn osisẹ NHS nikan. A ko gba ẹlomiran laaye lati ka iwe yi.

**Tani o tun le ran mi lọwọ?**

Oogun

Bi dọkita rẹ ba fẹ ki o lo awọn oogun kan, yoo kọ iwe ilana oogun ti a npe ni 'Prescription' fun ọ. Mu eyi lọ si ọdọ awọn ti nta oogun. Lati gba iwe ilana oogun naa lọfẹ, o nilo fọọmu HC2. Awọn onimọ nipa oogun lilo, ti a npe ni 'Pharmacists', le gba ọ niyanju nipa iwosan aarun keekeke. A le ri awọn oogun kan ra ni ile-itaja oogun laigba iwe ilana oogun yi, eyi si kan awọn oogun ara riro, ati awọn oogun ikọ.

Itọju eyin ati ẹnu

Bi o ba ni aarun kan nipa eyin rẹ, o gbọdọ ri dọkita ti nse itọju eyin ati ẹnu, ti a npe ni 'dentist'. Ki o to le ri itọju gba fun eyin rẹ, o gbọdọ kọkọ fi orukọ silẹ pẹlu dọkita olutọju eyin ati ẹnu. Bi o ba ni isoro nipa fifi orukọ silẹ pẹlu olutọju eyin ati ẹnu yi, o le lọ ri awọn NHS Direct, tabi awọn osisẹ ilera ni agbegbe rẹ.

Iriran oju

Bi o ba nilo lati se ayẹwo oju rẹ, tabi o fẹ gba jigi iriran titun, se eto lati ri dọkita ti ntọju oju. Awọn wọnyi ni ile-isẹ kaakiri aarin ilu. Fọọmu HC2 ti mu sisan owo fun ayẹwo oju ati fun awọn orisi jigi kan kuro, beere fun alaye lọwọ dọkita oju naa.

**Nigbati a ba ti ti ilẹkun ile-iwosan GP rẹ**

A maa nsi ilẹkun ile-isẹ GP lati aago mẹjọ aabọ (0830) titi di aago mẹfa aabọ irọlẹ (1830), lati ọjọ aje si ọjọ ẹti. Ni awọn akoko ti o ku – ni alẹ, ni ọjọ abamẹta, ọjọ aiku ati ni awọn ọjọ isimi pataki (public holidays) – oluranlọwọ dọkita ma nwa ni itosi fun awọn aisan pajawiri ti ko le duro de igbati a o si ilẹkun ile-isẹ dọkita rẹ.

Lati ri iranlọwọ, o le pe nọmba awọn osisẹ asiko-ti-o-rekọja ni agbegbe rẹ, eyiti a kọ si isalẹ yi, wọn yoo si gba ọ niyanju lati ori foonu. Wọn le sọ ile-iwosan GP ti o le lọ fun ọ, osisẹ ilera kan si le wa si ile rẹ.

O si tun le pe NHS Direct lori 0845 46 47, fun imọran nipa ailera, tabi fun <u>atilẹyin nipa ailera, nigbakugba ti ile-iwosan dọkita rẹ ba wa ni titi pa.</u> Ki yoo na ọ lowo pupọ bi o ba lo foonu agbesilẹ (landline), fun apẹẹrẹ, foonu ti a kọ sọọbu fun, ju pe ki o lo foonu alagbeka lọ.

Bi o ko ba gbọ ede gẹẹsi, NHS Direct ati awọn osisẹ asiko-ti-o-rekọja le ba ọ wa olutumọ-ede. Ohun ti o ni lati se ni wipe ki o darukọ ede ti o gbọ, ni ede gẹẹsi, nigbati o ba pe wọn lori foonu. Bi o ko ba le sọ ede gẹẹsi rara, jẹki ọrẹ tabi ẹbi rẹ, tabi osisẹ alatilẹyin kan ba ọ pe ibiti o fẹ pe, ki o si duro de igbati olutumọ-ede yoo le ba ọ sọrọ lori foonu naa, ki o to sọ ohun ti o nse ọ. A o beere awọn ohun kan lọwọ rẹ, gẹgẹbii orukọ rẹ ati adirẹẹsi rẹ: alaye yi se pataki, a ki yoo si sọ ohun ti o ba sọ fun ẹlomiran.

Lati pe NHS Direct fun imọran nipa ailera, pe:0845 46 47
Lati pe ile-isẹ asiko-ti-o-rekọja ni agbegbe rẹ, fun iranlọwọ nipa ailera nigbati ile-iwosan GP rẹ ba ti ti ilẹkun, pe:

**Ohun ti o le se nigba pajawiri**

Nigba pajawiri, bi iwọ tabi ẹnikẹni ti nba ọ gbe ba ni ailera ti o le jojo, eyiti ko see fi silẹ di igbati a ba si ilẹkun ile-iwosan GP, o le pe 999 (lọfẹ) fun ọkọ ti a fi ngbe awọn alaisan, o si tun le lọ si ẹka ti nri si Jamba ati Pajawiri ni ile-iwosan ti o wa ni agbegbe rẹ. Sugbọn, eyi wa fun igba pajawiri nikan. Mase lọ si ẹka ti nri si Jambaa ati Pajawiri fun awọn ailera keekeke.

Ẹkunrẹrẹ alaye nipa GP tabi nipa awọn ajọ ti nri si ilera awọn ti o salọ si ilu miiran fun aabo, ni agbegbe rẹ:

**ABOUT THE NHS**
**YORUBA**
**OCTOBER 2005**
**HEALTH & HOUSING RESOURCES. UNIT 39 CONCOURSE HOUSE**
**DEWSBURY ROAD LEEDS LS11 7DF**
**T. 0113 2770999 F. 0113 2704753**
email <**1kelvin@healthandhousing.org**>